# Pẹ̀lú Ètò Ọ̀làjú; Kí ni Ọjọ́ Ọ̀la Èdè àti Àṣà Yorùbá

*Mákindé, S.O., PhD*

**Aṣamọ**

*Bí a bá wo bí ọfun ṣe tóbi bu òkèlè, onígẹ̀gẹ̀ yóò mi iyán tàwotàwo. Bẹ́ẹ̀ sì ni pé àìláṣọ lọ́rùn Pààká, ó tó àpérò gbogbo ọmọ eríwo. Bí a bá wo ipò tí ètò ọ̀làjú wà ní ilẹ̀ wa ati ìhà ti àwùjọ òde oní kọ sí àṣà àti èdè Yorùbá, ọjọ́ iwájú yóò kọ ni lóminú gan-an ni. Àmọ́ bí gbígbó ajá kò bá tilẹ̀ mú olè, ariwò rẹ̀ yóò jí olówó rẹ̀ kalẹ̀. Èyí ló fàá tí bébà àpilẹ̀kọ yìí fi ṣe àgbéyẹ̀wò ohun tí àṣà àti ọ̀làjú jẹ́, àwọn àbùdá adání àṣà, ẹ̀kọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá, ipò tí àṣà Yorùbá wà lọ́jọ́un àti ipa tí ọ̀làjú kó lorí àṣà lóde òní. Lẹ́yìn èyí ni a dábàá àwọn ohun àmúṣe àti ojúṣe fún òbí, akẹ́kọ̀ọ́, olùkọ́, ìjọba, ilé iṣẹ́ ìròyìn ati àwujọ lápapọ̀ láti ṣe àgbéǹde fún àṣà àti èdè Yorùbá.*

## Ìfáárà

Ètò tàbí ìwà ọ̀làjú tọ́ka sí ìyípadà tàbí ìdàgbàsókè tí o lè dé bá bi a ti ń ṣe nǹkan pàápàá ohun tí ó jẹ mọ́ àṣà àti iṣe ní àwùjọ tí a ń gbé. Gẹ́gẹ́ bí Arówólò (2010) ti ṣàlayé, ètò ọ̀làjú tọ́ka sí òdíwọ̀n ìdàgbàsókè tí àwujọ kan ní lórí ètò kan pàtó láwùjọ. O tún ṣàlàyé pé a lè fi àṣà pe ìlàjú tàbí ọ̀làjú nítorí pé àwọn ohun tí wọn tọ́ka sí jọra púpọ̀.

A tún lè tọ́ka sí ètò ọ̀làjú sọrí orílẹ̀ èdè tí a ń perí. Àpẹẹrẹ ni: ètò ọ̀làjú ilẹ̀ Amẹ́ríka; ètò ọ̀làjú ilẹ̀ Ṣáínà; ètò ọ̀làjú ilẹ̀ Afíríkà tàbí kí a tilẹ̀ sọ nípa ètò ọ̀làjú ilẹ̀ Nàìjíríà. Ìlàjú tàbí ìdàgbàsókè a máa gbéwọ̀n ju ara wọn lọ. A lè sọ pé ètò ọ̀làjú ilẹ̀ kan ti gòkè àgbà ju ti ibòmíràn lọ. Àwùjọ tí ó ń ṣàmúlò ẹ̀rọ ìgbàlódé fún iṣẹ́ ọ̀gbìn yóò ní ìkórè púpọ̀ ju èyí tó ń ṣàmúlò ètò ọ̀gbìn ọjọ́un. Bí a bá ṣe àwòfín, àṣà gbòòrò ju ìlàjú tabí ọ̀làjú lọ.

Ohun ti´a ń pè ni àṣà gbòòrò púpọ̀. Àṣà jẹ́ àgbaríjọpọ̀ ìgbésí aye´àwọn ènìyàn kan ní àwùjọ kan ni´pàtó. Àṣà jẹ mó ẹ̀kọ́ ìgbésí aye´ẹ̀da´ti´ó ń fi ìṣesí

tàbi ìwà àwùjọ ti´a ń wí yìí hàn ni´ti pe´àwùjọ náà ni ìgbàgbọ́ nínú rẹ̀, wọ́n si`fi ń kọ́ ọmọ wọn láti ìran kan de´òmíràn. Àṣà ní í ṣe pẹ̀lú nǹkan wọ̀nyìí:

> ìgbàgbọ́, ìwà, ìhùwàsí ẹ̀da´, iṣẹ́ ọnà, ètò ile´gbígbe´, orin, ere ìbílẹ̀, ìbáṣepọ̀ láàrin àwùjọ, ìhà ti´a kọ si´nǹkan, ìmọ̀ ẹ̀rọ àti àwọn ìgbékalẹ̀ èniyàn láwùjọ. Síwájú si´i, oúnje ti´àwọn èniyàn naà ń jẹ, ọ̀nà ti´wọ́n ń gbà sè é, ọ̀ṣọ́ ṣíṣe wọn, ìgbàgbọ́ wọn nipá isẹ̀da´aye´, àṣà wọn nípa ìgbeyàwó, ọmọ bíbí àti ìsọmọlórukọ, ìsìnkú, ọ̀nà ìranra-ẹni-lọ́wọ́, ìṣèjọba wọn, àwọn ohun tí wọ́n fẹ́ràn pẹ̀lú èèwọ̀ wọn (Orji & Ihenacho in Makinde´, 2013).

Ti´a ba´si ń sọ ni´ti ìran Yorùbá, agbègbè Ìwọ̀ Oòrùn Nàìjìrìà ni Olódùmarè fi jíǹkì wa nínú èyi´ti Ìpínlẹ̀ Kúárà àti Kogi wà. A tún lè ri´àwọn ìran Yorùba´ ni´àwọn Ìpínlẹ̀

Ẹdo, Delta, àti ni àwọn oríl̀ẹ̀-èdè bí'i Bini, Tógò, Sàró, Ivory Coast, Gúúsù Amẹ́ríkà, Bùràsiíl̀i,` Iwò-Oòrùn Indies, Kúbà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (Makinde,´ 2018).

**Ìpín sí ìsọ̀rí àṣà Àṣà lè jẹ mọ́:**

a. Àwọn ohun tí a lè fi ojú rí (Ajẹmọ́ ohun èlò)- Material Culture

b. Àwọn ohun tí a kò lè fi ojú ri´ (Aláìjẹmọ́ ohun èlò) - Nonmaterial culture

**a. Àṣà Aláìjẹmọ́ ohun ti´a lè fi ojú ri´(ajẹmọ́ ohun èlò)**

Àwọn ohun èlò wọ̀nyiì ni gbogbo nǹkan ti´àwùjo níl̀ò fún ìgbádùn, ìtelọ́rùn àti ààbò wọn. Àpẹẹrẹ ni ile´, àwọn ohun èlò iṣẹ ọ̀gb̀ìn, ti ogun jíjà, ọdẹ ṣíṣe, aṣọ àti àwọn ohun ọnà Yorùba´bi´irin riŕọ, aṣọ híhun´, aró dídá, ère gbigb́ẹ́, igba´fínfín, ìṣònà, àgbẹdẹ , ẹní hihun´, aṣọ híhun, ade´sísín, góòlù fif̀ọ̀, il̀ù sísè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Lará àwọn ohun èèlò tí a ń lò ni igi, amọ̀, òkúta idẹ, òwú, aṣọ, ẹran, ìwò`, igba´, ewe´imọ̀, aró, àgbọn, èkùrọ́, ìkarauǹ. Àwọn miìràn gbà pe´ ìsòrí àṣà yiì jẹ mó ìmọ̀-ẹ̀rọ. Ìdàgbàsókè máa ń dé bá àwọn ohun èlò wọ̀nyiì bí´ọgbọ́n àti ìmọ̀ àwùjọ bá ti ń ga sí.

**b. Àṣà Ajẹmọ́ ohun èlò (tí a kò lè fi ojú ri`)**

Àfòyemọ̀/àfọkànrò ni àwọn ohun ti´a ń tọ́ka sí níbí.

A maá ń kọ́ nípa wọn ni, wọ́n si fi bẹ́ẹ̀ di barakú fún àwùjọ nibí ti´a ti ń ba´wọn pàdé. Àpẹẹrẹ wọn ni: ìkíni, ìgbàgbọ́, èdè, ìwúre, orin, ijó, ìtàn àti ọ̀nà ti´a ń gbà sọ ọ́ tàbi´kọ́ àwọn èwe, ọ̀nà ti´a ń gbà rań aṣọ àti bi´a ṣe ń wọ̀ ọ́, òfin àti ọ̀nà ìṣèlú. Nínú gbogbo nǹkan wọ̀nyí, èdè ló ṣe pàtàkì jù lọ. Lónìí, Gẹ̀ẹ́sì àti Faransé ni èdè ìjọba ní Nàìjiŕià àmọ́ il̀ò èdè ibil̀ẹ̀ ni ó lè mú àṣà ìbíl̀eẹ̀ dàgbà. Èdè ṣe pàtàkì nítorí pe´èdè la fi ń ṣàlàye´ àṣà. Èdè eléd̀è kò ṣe e´ṣàlàye´àṣà aláṣ̀à. Bi´a ba´fi èdè eléd̀è ṣàlàye´àṣà aláṣ̀à, àṣà kò pe´mọ́ nìyẹn.

**Àwọn Àbùdá Àdání Àṣà**

Àwọn àbùda´àdání àṣà ni:

- Àṣà kì í ṣe àmútọ̀runwa,´ kikọ́ ni a ń kọ́ àṣà latí ìran kan de´òmíràn
- Àṣà kò dúró lójú kan, ó maá ń yi´padà bi´àwùjọ ti ń yi´padà ni. Kì í ṣe ohun tó burú bí a bá rí ohun tí ó dára nínú àṣà ilẹ̀ mìíràn tí a sì ṣàmúlò irúfẹ́ àṣà bẹ́ẹ̀. Èyí ló fàá tí àṣà fi màa ń wọ inú ara wọn.
- Awùjọ kọ̀ọ̀kan ló ni´àṣà tirẹ̀, àṣà la fi ń da´àwùjọ mọ̀.
- Ètò maá ń wà nínú àwùjọ, iyípadà tó ba´ṣẹlẹ̀ sí ètò kan maá ń ní ipa lóri ´àwọn ètò miíràn lawùjọ; - bí àpẹẹrẹ, ìyípadà nínú ètò ìjọba yóò fa ìyípad̀à ba´ ètò ọrọ̀ aje´, ètò èkọ́, ètò id̀ajọ́, ojúṣe ọkùnrin/obìnriǹ lawùjo àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àṣà gbòòrò ju ọ̀làjú lọ, ọ̀làjú náà ní àwọn àbùdá àdání tí àṣà ní.

**Ipò ti àṣà Yorùbá wà lónìí**

Ṣíwájú wíwá àwọn òyìnbó amúnisìn, ìran Yorùbá kò kẹ̀rẹ̀ rárá nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ àti idàgbàsókè ohun àmúṣọrọ̀. Òkúta wà (ẹ̀ta sàgodo, ẹ̀ta òkò tàbí ẹ̀ta afúyẹ́ àti ẹ̀ta agúnwínwín) tí àwọn baba wa ń sọ di irin ti àwọn alágbẹ̀dẹ tàbí oníṣẹ́ arọ́ fi ń rọ ohun èlò ọ̀gbìn àti iṣẹ́ àgbẹ̀ (àdá, ọkọ́, ààké, dòjé, akọ́rọ́ ati ọ̀bẹ); ohun èlò ààbò (ìbọn, idà, agogo, ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ àti àwọn ohun èlò mìíran); iṣẹ́ abẹ ati ìwòsàn (abẹ́ mímú wà fún iṣẹ́ abẹ,abẹ́rẹ́ olúkòǹdó wà fún orí fífá); iṣẹ́ gbẹ́nàgbẹ́nà (òòlù, ayùn, ìṣó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ). Ọ̀pọ̀ ohun èlò ni àwọn alágbẹ̀dẹ tàbí oníṣẹ́ arọ́ ń fi irin rọ. Bí a bá ṣe ọ̀fíntótó nípa àwọn iṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùba, yóò hàn sí wa pé ìran Yorùbá kì í ṣe èrò ẹ̀yìn (Adéníji, n.y; Akinyẹmí, n.y.)

Latàrí ogun jijà, ìjọba amúnisìn, òwò ẹrú, ẹ̀sìn láti ilẹ̀ òkèèrè, ìrin-àjò àti ẹ̀kọ́ ìgbàlóde,´ ìyipadà ti de´ ba´ àṣà ibìlẹ̀ Yorùba´ lọ́pọ̀lọ́pọ̀. Díẹ̀ nínú àwọn ọ̀nà ti´ ìyípadà ti de´ ba´àṣà Yorùba´ni a lè mẹ́nubà ninú ọ̀rọ̀ àpilẹ̀ṣọ yìí nítorí àyè kò sí tààrà.

**Ìyípadà nínú ẹ̀kọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá**

Nínú ẹ̀kọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá, èròǹgbà gbogboogbò ni kí ọmọ Yorùba´ lè jẹ́ ọmọlúàbí. Kókó mejé sì`ni èkọ́ ìbílẹ̀ Yorùba´ da´ le´ lóri´ (Fafúnwa,´ 1995).

- Ìdàgbàsókè ẹ̀bùn àmútọ̀runwá ajẹmọ́ ara/okun ara tí ó máa ń jẹ yọ nínú ere ´ọmọde´, ere´ìdarayá, ijó, ìlúwẹ̀ẹ́´, igi gígùn, ẹkẹ /ìjàkadì abbl.
- Ìdàgbàsókè nínú ìwà ọmọlúàbí/rere: jíjẹ́ olóòótó sí gbogbo ènìyàn.

**a. Bi´a ti ń kọ́ ìwà ọmọlúàbí**

Obidi (1990) nińú Makinde´(2013) tọ́ka si´àwọn ọ̀nà ti´a ń gbà kọ́ àṣà àti ìwà ọmọlúàbí:

a. Àwòkọ́ṣe: A maá ń kọ àṣà nipá àwòkóse.
   i. "Ẹṣin iwájú ni tẹ̀yìn ń wò sáré"
   ii. "Òwú tí ìyá bá gbọ̀n lọmọ ó ran"

b. Ìlànà ìfiyéni/ìkọ́ni tààrà: ìkọ́ni pẹ̀lú àlàyé ọ̀rọ̀ àti ìṣehanni, kí a sì ní kí ọmọ náà ṣe bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́.

d. Ẹ̀kọ́ láti inú ìtàn àlọ́– àpẹẹrẹ ni ìtàn ọba alárán-an àti ẹyẹ kìn-ìn-kin.

e. **lànà Eèwọ̀** - latí kọ́ ọmọ ni ìmọ́tótó, àlàáfíà àti ìmọrírì ẹ̀mí ènìyàn (Odù tó bí Orí-Ọni)

ẹ. **Ilànà Idẹ̀wò tàbi´ Ìdánwò:** Ìyá lè fi ẹran/ẹja díndín tàbí owó tí ó ti mọ iye tí ó jẹ́ sí ibi kan, kí ó sì rí i dájú pé kò sí ẹlòmíràn tí ó wọ ibẹ̀. Òun yóò rán ọmọ tí a ń ṣe ìdánwò fún láti lọ síbẹ̀. Bí ẹran/ẹja tàbi owó náà bá dín ní iye tí ìyá kà síbẹ̀, a jẹ́ pe ọmọ ọ̀ún ń jalè nìyẹn. Irú ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò jìyà, yóò máa gba ìbáwí títí yóò fi yí padà ni.

- **Ìdàgbàsókè ajẹmọ́ṣẹ́ ọpọlọ:** nínı́ìmọ̀ nípa ìtàn ìlú, àwọn òkè, ọ̀gbun,

òkun, ọ̀sà, odò, orúkọ igi, ewé, ewébẹ̀, ohun ọ̀gbìn gbogbo, ẹranko, ẹja, ẹyẹ , kòkòrò, orin ìbílẹ̀, àwọn ìbọ abbl.

- **Ìbọ̀wọ̀fágbà àti ojúgbà ẹni**: Ìkíni (ìdọ̀bálẹ̀ fọ́kùnrin/ìkúnlẹ̀ fóbìnrin),ọ̀wọ̀ fún ọba/ìjòyè/ajunilọ , ìtẹríba fún gbogbo ènìyàn, pípa òfin àwùjọ mọ́.
- **Ìdàgbàsókè nínú iṣẹ́ ìbílẹ̀**: Àpẹẹrẹ iṣẹ́ ìbílẹ̀ ni a ti mẹ́nubà nínú àlàye ́tí a ṣe nípa ohun tí àṣà jẹ mọ́.
- **Kíkópa nínú ìdàgbàsókè àwùjọ ẹni**: kíkọ́ gbọ̀gàn ìlú, yíyẹ ọ̀na ìgbẹ́ ọdẹ lásìkò ìwúyè ọba/ọdún ibílẹ̀; fífi ojú sí àṣà tó rọ̀ mọ́ ìwọṣọ, ètò ìgbeyàwó, ìsọmọlórúkọ, kíkọ́/títọ́ ọmọdé, ètò ìsìnkú, àṣà ìran-ara-ẹni=lọ́wọ́ abbl.

Lónìí, ìmọ̀ ti gbòòrò ju àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyìí lọ, ṣùgbọ́n gbogbo àwọn kókó méjèèje ni wọ́n ṣì wúlò fún àwùjọ Nàìjìríà òde òní àti ti àgbayé ́ pẹ̀lú. Ìbáṣepọ̀ alọ́majàà ló wà láàrin èdè, àṣà, àti àwùjọ . Èdè la fi ń kọ́ ẹ̀kọ́ láwùjọ , kò sí àwùjọ ti ́kò ni àṣà àti èdè tirẹ̀, èdè náà la fi ń ṣàlàye ́ àṣà gẹ́gẹ́ bí a ti sọ tẹ́lẹ̀. Ṣùgbọ́n ó ṣe ni láànú pé ẹ̀kọ̀ ìbílẹ̀, pàápàá ẹ̀kọ́ ilé ti sọnù ní ọ̀pọ̀ ile, ṣàṣà ni ile ́ ẹ̀kọ́ tó kàá sí pàtàkì. Èyí ló fàá tí àwùjọ fi kún fún ewu tí àwọn ìwà ìbàjẹ́ fi wọ́pọ̀ ní àwùjọ òde òní.

Èdè elédè ni ogunlọ́gọ̀ ọmọ Yorùbá ń sá mọ́ lonìí.

Ètò mọ̀lẹ́bí jẹ́ ohun tí a ní igbàgbọ́ ninu rẹ̀ nínú àṣà wa. Ṣùgbọ́n àṣà aláṣà tí a ń sá mọ́ kò fàyè gba èyí. Kóńkó jabele ni tiwọn. Èmi àti aya mi àti ọmọ nìkan ni. Àwọn mìíràn kò tilẹ̀ fẹ́ ọmọ lọ́dọ̀ tiwọn. Ìbáṣepọ̀ agbègbè di ohun tí o sọnù láàrin wa.

Ètò ọ̀làjú – tàbí ojú àlàsódì ló fàá tí gbogbo àwọn tó wà ni ìgbèríko tó yẹ kí wọn máa ṣiṣẹ́ oko fi ìgbèríko sílẹ̀ láti máa wá iṣẹ́ lébìrà ní àwọn ilé iṣẹ́ nlá ní ìgboro. Ìwà ìbàjẹ́ ní ibi gíga èyí tí kò jẹ́ kí ìjọba fi àwọn ohun amáyédẹrùn sí ìgbèríko ló fàá tí àwọn ti wọ́n ń bẹ ní ìgbèríko kò fi lè dúró nibẹ̀.

### b. Àìníṣẹ́lọ́wọ́

Lọ́jọ́un, gbogbo ọmọ Yorùbá ló mọ ìyí àṣekará. Iṣẹ ́àgbẹ̀ niṣẹ́ ilẹ̀ wa. Kò sí àìníṣẹ lọ́wọ́. Yàtọ̀ sí iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ ́ìbílẹ̀ tún wà lọ́kan-ò-jọ̀kan, gẹ́gẹ́ bí agbègbè tí Ẹlẹ́daá sọ ọmọ Káàrọ̀-oò-jíire lọ́jọ̀ sí. Àwọn tó ń gbe ́lagbègbè odò a maá ṣiṣẹ́ apẹja, àti awakọ̀ ojú omi pẹ̀lú ọkọ̀ kíkàn; àwọn tó ń gbé nínú ilẹ̀-igbó ńlá níbi tí a ti rí àwọn igi tó ti gbó a maá ṣiṣẹ́ agbẹ́gẹ́dú/alapakó (iṣẹ́ ayùn), iṣẹ́ gbẹ́nà-gbẹ́nà ń bẹ, iṣẹ ́ ilé-mímọ, ìṣọ̀nà, àgbẹ̀dẹ bàmù, agbégilére, ọtí pípọn, igbá fínfín, aṣọ híhun, ọṣẹ fífọ̀, epo ṣíṣe, ọdẹ ṣíṣe, ìlù sísè, iṣẹ ́àyàn, ìkòkò mímọ, gaàrí yíyan, èlùbọ́ ṣíṣe, irun dídì/gígẹ̀, ẹran dídà, ẹni híhun, òwò ṣíṣe àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ki ́ló fàá tí àìníṣẹ́-lọ́wọ́ fi pọ̀ láwùjọ Nàìjíríà òde – òní? Ìṣòro àìníṣẹ́ lọ́wọ́ yìí ni okùnfà àfikún onírúurú iṣẹ́ ọwọ́ (lará èyí tí a ti rí àwọn iṣẹ́ ìbílẹ̀) sí inú kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù àwọn ilé ẹ̀kọ́ gíga ní ilẹ̀ Nàìjíríà kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́-gboyè lè di agbani-síṣẹ dípò kí wọ́n maá wá iṣẹ ́kaàkiri.

**d. Ìbọ̀wọ̀fágbà**

Bí ọmọ Yorùbá yóò bá kí àgbàlagbà, bí ó ba´ jẹ́ ọmọkùnrin, yóò dọ̀báĺẹ̀ gbalaja, ọmọbìnrin a sì kúnlẹ̀ wọ̀ọ̀. Ibọ̀wọ̀-fágb́à ni. Fífí ọ̀wọ̀ fún àwọn àgbà jẹ́ ojúṣe gbogbo ọmọ Yorùbá àtàtà (Idòwú, 1982 nínú Makindé, 2013). A kìí kí ọba níb́ẹ̀rẹ̀ tàbí nínàró, ìbọ̀wọ̀-fágb́à ni. Ọmọ Yorùbá a maá gba ẹrù lórí/ĺọ́wọ́ àgbà, a maá didè fún àgbà latí jókòó. Bí yóò ba´pa òwe níwájú àwọn àgbà, yóò júbà wọn. Tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ laya ń gbé oúnjẹ fún ọkọ lọ́jọun. Àwọn àgbà kìí sì í ṣe láńgbá-láńgbá. Àwòkọ́ṣe ni wọ́n jẹ́ fáwọn tó ń bọ̀ lẹ́yìn.

Báwo ni ọ̀rọ̀ tí rí lónìí? Ọmọ mélòó ni ń dọ̀bálẹ̀ tàbí kúnlẹ̀ kí àgbà lónìí? Akẹ́kọ̀ọ́ mélòó ni ń sáré lọ gba ẹrù lọ́wọ́ olùkọ́. Ilé ayé ti di fẹ́lẹfẹ̀lẹ. Ọmọ ń pe baba lórùkọ, wọ́n dojú àṣà dé porogodo.

Lónìí ọ̀pọ̀ ọmọ Yorùbá ni kò tilẹ̀ mọ bí a ti ń ki ni ní onírúurú ìgbà àti àkókò, wọn kò tilẹ̀ ṣe tań latí dọ̀báĺẹ̀ tàbí kúnlẹ̀ fágbà.

**e. Ìyípadà nínú àwọn àṣà mìíràn:**

- Ìgb̀éyàwó: Ọ̀rọ̀ nípa ìbáĺé tó ṣe pàtàkì ní gbogbo àwùjọ Yorùba´ lọ́jọ́un kọ já mọ́ nǹkan mọ́ lọ́dọ̀ ọ̀pọ̀ èniyàn!
- Ìkọ̀síĺẹ̀ tọkọ-taya ń wọ́pọ̀ lónìí nítorí ọ̀pọ̀ kò ṣe é bí àwọn àgbà ti ń ṣe e´. Ìran Yorùbá kì í fi ọ̀rọ̀ mọ̀lẹb́í ṣere´
- Oríkì àti oríĺẹ̀: Ìwọn perete ni ọmọ Yorùbá tó mọ ohun tí oríkì àti orílẹ̀ jẹ́.

**ẹ. Orúkọ**

Ọ̀pọ̀ ọmọ Yorùbá kò fẹ́ràn orúkọ tí a sọ wọ́n. Àlàdé yóò di Alardey; Olúṣínà yóò di Horlushinar. Wọ́n ń tijú àṣà wọn ni. Ọ̀jọ̀gbọ́n Emman Kweegyi Aggrey ni ọdùn púpọ̀ sẹ́yin sọ pé:

> I am black and proud; I am proud of my color. Anyone who is not proud of his color is not fit to live.

Ìyẹn ni pé, "Inú mi dùn pé a dá mi lénìyàn dúdú; mo ní ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú àwọ̀ mi, ẹni tí kò bá ní ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú àwọ̀ rẹ̀, kò yẹ láti máa gbéle ayé".

ii. Ojúlówó orúkọ ìlú àti àdúgbò púpọ̀ ni a ti sọnù nítorí àìkáràmásíkì àṣà àti èdè wa.

Àpẹẹrẹ díẹ̀ ni ìwọ̀nyí:

- Abẹ́sàn ni a sọ di Abẹ̀sán
- Aláwùsá ni ọ̀pọ̀ ń pè ní Aláwúsá.
- Ìjẹ̀bú-Igbó kì í ṣe Ìjẹ̀bú-Ìgbò
- Amúkookò kì í ṣe Amùkòkò
- Agbọ́tẹ̀kúyọ̀ kì í ṣe Agbọ́tikúyọ̀
- Èkó Àketè kì í Èkó Àkéte

iii. Àṣìpè ọ̀rọ̀ inú Bíbélì

Nínú Jẹ́nẹ́sísì 1: 2 a kà ni Gẹ̀ẹ́sì báyìí pé:

> "And the earth was without form and void: And the Spirit of God moved upon the face of the waters" (KJV). [Ayé sì wà ní júújúú, ó sì ṣófo; òkùnkùn sì wà lójú ibú: Ẹ̀mí Ọlọ́run sì ń rà bàbà lójú omi.]

Àṣìkà ni ká màa sọ pé "Ayé si wà ní júujùu". Ibi tí a kó ẹrù àti ohun èlò jánganjàngan sí láìlétò ló lè wà ní júujùu. Ayé ṣófo nígbà nàà, "júújúú" ni.

Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni o jẹ́ àṣìkà láti sọ pé "Ẹ̀mí Ọlọ́rún ń rá bàbà". Níwọ̀n ìgbà tí ó ṣe pé Ẹyẹ bí àdàbà ni a máa ń fi ṣàpẹẹrẹ Ẹ̀mí Mimọ́ nínú

Bíbélì, rírà ni ẹyẹ máa ń rà. Ẹyẹ kì í rá bàbà bí ọmọ ènìyàn ti ń ṣe nígbà tí ó bá ń kí ajunilọ tabí lati fi ìbà àti ìyìn fún Olú Ọ̀run.

Aṣako (backslider) kì í aṣáko (bush cutter). Ìyàtọ̀ wà láàrin kikankikan (furiously as in running or speeding) tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀-àpọ́nlé oníbá (adverb of manner) àti "kíkankíkàn" (sower-sower) tí àwọn ẹ̀lòmíràn ń pè é.

### f. Ọṣọ́ Ṣíṣe

- Ìyípadàti dé bá aṣọ tí a ń wọ̀ lọ́kùnrin àti lóbìnrin
- Àṣà ilà bíb̀ù ti ń kasẹ̀ nílẹ̀
- Irun gígẹ̀ àti irun dídì ní ti ìbílẹ̀ ti ń kasẹ̀ nílẹ̀, irun jíjó ló ń gbaye´ kan.
- Ara bíbó jẹ ohun tí ó wọ́pọ̀ lásìkò yìí.
- Orin ìbílẹ̀, Ijó ìbílẹ̀, ìlù ìbílẹ̀ ti di ohun tí ọ̀pọ̀ kò kà sí mọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

### 5. Àbọ̀ Ìwádìí Ibi Iṣẹ́ fún Ọ̀nà Ìṣàmúlò Èdè Yorùbá

Nínú àbọ̀ ìwádìí tí Ibi Iṣẹ́ fún Ọ̀nà Ìṣàmúlò Èdè Yorùbá gbé jáde ní ibi Àjọ̀dún Ìdàgbàsókè Ìran Yorùbá Lágbàáyé Alákọ̀ọ́kọ́: Ìpàtẹ Ìwé lórí Yorùbá, Olùdarí ibi iṣẹ́ náà tọ́ka sí àmì méjì pàtàkì tí ó ṣàfihàn pé èdè Yorùbá wà nínú àwọn èdè tí ó lè parun:

i. Ìhà tí àwa elédè kọ sí èdè wa :
   - Àwọn ọ̀mọ̀wé ọmọ Yorùbá kan wà tí wọn kọ̀ láti máa sọ èdè Yorùbá.
   - Ó lójú ibi tí a ti le lo èdè Yorùbà fún íbáraẹnisọ̀rọ̀
   - Àwọn òbí kan kò tilẹ̀ fẹ́ kí ọmọ ó sọ èdè Yorùbá nílé.
   - Àwọn ọ̀dọ́ pàápàá ń yí orúkọ wọn padà kí ó lè jọ ti àwọn ará iwájú omi.

ii. Àwọn àmì ajẹmọ́ ètò ẹ̀kọ́

- Ìwọn péréte ni àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n tí ń keẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́lọ́wọ́ ni àwọn Ilé Ẹ̀kọ́ Olùkọni Onípò Kínní (NCE) méjìlélọ́gbọ̀n (32) àti Yunifásítì mọ́kànlá (11).
- Àpapọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ Ilé Ẹ̀kọ́ Olùkọni Onípò Kínní (NCE) tí wọ́n ń kọ́ èdè Yorùba bí èdè kínní (L1) jẹ́ 994
- Àpapọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ Ilé Ẹ̀kọ́ Olùkọni Onípò Kínní (NCE) tí wọ́n ń kọ́ èdè Yorùba bí èdè kejì (L2) jẹ́ 76

- Àpapọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní Ilé Ẹ̀kọ́ Olùkọni Onípò Kínní (NCE) ṣùgbọ́n tí wọ́n ń kọ́ èdè Yorùba láti gba oyè B. A. ẸẸ̀D jẹ́ 206
- Àpapọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá ní Yunifásítì jẹ́ 1074
- Àpapọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá onímọ̀ gíga (Postgraduate) Yunifásítì jẹ́ 101
- *Apapọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá = 2,451 (Irínwo-lélẹ́gbàá àti òkàn-lé-láàdọ́ta)*

Síwájú sí i, àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga ilẹ̀ okèèrè wà tí a ti ń kọ́ èdè Yorùbá:

i. Amẹ́rikà = 33
ii. Bùràsíìlì = 03
iii. Kúbà = 01

Bí a bá wo iye àwa tí a jẹ́ ọmọ Yorùbá lágbàáyé (mílíọ̀nì bí i 56 ní Nàìjíríàà, mílíọ̀nì bí i 200 lágbàáyé) sí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga, ó kéré púpọ̀.

### 6. Ipa tí àṣà lè kó nínú idàgbàsókè àwùjọ Yorùbá Àwọn iṣẹ́-ìbílẹ̀ wa ṣì wúlò púpọ̀

A lè pín wọn sí ọ̀nà mẹ́ta:

a. Iṣẹ́ Àgbẹ̀: ọ̀gbìn, ẹja sísìn/pípa àti ẹran ọ̀sìn abbl.
b. Òkòwò àti iṣẹ́ ọnà: Aṣọ híhun/ẹní híhun/apẹ̀rẹ̀ híhun, àgbẹdẹ, ọdẹ agbẹ́gilére, igbá fínfín, asíndẹ mádé, ilé kíkọ́, ìlù lílù, irun ṣíṣe, ọkọ̀-kíkàn, apẹ/ìkòkò mímọ, ìṣọ̀nà, ọṣẹ pípò, orin kíkọ, irin ríro, ẹmu dídá, ọtí pípọn.
d. Àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ mìíràn: Iṣẹ́ ìṣègùn, iṣẹ́ abọrẹ̀, iṣẹ́ awo, ìṣèlú, baálẹ̀, ìjòyè, owó-bodè tàbí owó-orí gbígbà, adájọ́, ìṣọ́/ẹ̀ṣọ́ ìlú, ọdẹ-ìgboro; ọdẹ igbó.

e. Àwọn Iṣẹ́ Ajẹmédè

- Iṣẹ́ Olùkọ́
- Aáya ògbúfọ̀
- Àlùfáà
- Òǹkọ̀wé
- Òǹtẹ̀we àti Ilé iṣẹ́ Ìròyìn
- Akópa nínú ere oniṣe/òṣèré
- Ẹni tí ó ń gbé fíìmù/sinimá àgbéléwò jáde
- Alágá ìdúró/ Alága ìjókòó níbi ìgbéyàwó
- Atọ́nà níbi àṣeyẹ – MC
- Ilé-Iṣẹ́ Ìròyìn àti móhùn-máwòrán
- Akéwì àti ọ̀kọrin lédè Yorùbá: Àpẹẹrẹ; Lánre Adépoọ̀jù, Ebenezer Obey, Suny Adé, Àyinlà Kolington, abbl
- Sísọ àwọn ibi pàtàkì – pàtàkì di ibi ìgbafẹ́ tó lè mówó wá.

**Ìkádìí**

- Bí a óò ba´se àgbéǹde àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá a gbọ́dọ̀ gbe´èdè Yorùbá laruǵẹ nínú ile´wa, ilé-ìwé, ní ìpínlẹ̀ àti lóríl̀ẹ̀ èdè lapapọ̀. Àwọn òbí gbọ́dọ̀ máa bá àwọn ọmọ wọn sọ èdè Yorùbá.
- Pípè/sísọ àwọn ọmọ Yorùbá ní orúkọ ìbílẹ̀ wọn ṣe pàtàkì.
- Kikó àwọn ọmọ ní iṣẹ́ ìbílẹ̀ ní ile´ẹ̀kọ́ gbogbo ṣe pàtàkî.
- Àpẹẹrẹ ìwà rere láti ilé ilé-ẹ̀kọ́ àti àwọn aṣáájú ẹ̀sìn, ilé iṣẹ́ ìjọba, àwọn agbófinró àti ti ìṣèlú ṣe pàtàki.
- Gbígbé àwọn sinimá tàbí fììmù ajẹmọ́ ìwà ọ̀daràn, oníh̀òòhò jáde a máa ṣe àkóbá fọ́mọdé àtàgbà.
- Irúfẹ ètò yìí, Àjọ̀dún Yorùbá tàbí Ọ̀sẹ̀ Yorùbá ní àwọn ilé-ẹkọ́ wa níbi tí a ti ń ṣe ìdíje ajẹmédè, ajẹmásṣà àti ajẹmọ́ lítíréṣọ̀ èdè Yorùbá lérè púpọ̀.
- Ìlàkàkà láti fi èdè Yorùbá kọ́ gbogbo iṣẹ́´ní ile´ẹ̀kọ́ bẹ̀rẹ̀ láti ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ títí dé ilé-ẹ̀kọ́ gíga ti Yunifásítì bí a ti rí i ní àwọn oríl̀ẹ̀-èdè bí Jèpáànì, Jámànì, Faransé Rọṣíà. Ṣíṣe èyí yóò mú kí ọmọ Yorùbá ní ọgbọ́n àtinúdá èyí tí ó ṣe pàtàkì látí ṣe okùnfà iṣẹ́ àwarí tó yanranntí.
- Mímú èdè Yorùbá ní pàtàkì ní orílẹ̀ èdè àti ní àwọn ilé ẹ̀kọ́ ṣe kókó. Ó ṣe pàtàkì kí àwọn Ìjọba Ìpínlẹ̀ ni gbogbo ilẹ̀ Káààrọ̀-oò-jíire ó mú ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá ní pàtàkì ní àwọn ilé-ẹkọ wa gẹ́gẹ́ bí Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkó ti ṣe ní ọdún 2018 nígbà tí Gómìnà Akinwùmí Aḿbọdé ṣe ìfọwọsí àba´ Ilé-Ìgbìmọ̀ Aṣòfin pe´ ó di dandan kí gbogbo ile´-ẹ̀kọ́ ni Ìpínl̀ẹ̀ Èkó gbọ́dọ̀ ṣe àfikún ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá sínú kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù wọn, àti pe´gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ tí ó bá wọ ilé ẹ̀kọ́ gíga tí ó jẹ́ ti Ìpínl̀ẹ̀ Èkó ni yóò bá ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá pàdé nínú ẹ̀kọ́ wọn.
- Síwájú sí i, ó ṣe pàtàkì kí akẹkọ̀ọ́ tí yóò bá wọ ilé ẹ̀kọ́ gíga tí ó jẹ́ tiÌpínl̀ẹ̀ Èkó ó yege nínú ìdánwò àṣekágbá ti sẹ́kọ́ńdìrì kí ó tó lè ní àǹfààní láti wọ ilé ẹ̀kọ́ gíga ti Ìpínl̀ẹ̀ Èkó. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ó di èèwọ̀ láti fi ìyà jẹ ẹnikẹ́ni tàbí akẹ́kọ̀ọ́ tí ó ba´sọ èdè Yorùba´yal̀à ní ibi iṣẹ´ tàbí ní ilé ẹ̀kọ́ (Mákindé, 2018).

Bí a bá mú ẹ̀kọ́ èdè ní pàtàkí, a mú àṣà ní pàtàkì nìyẹn! Èdè àti àṣà dàbí apá mejì tí ẹyẹ fi ń fò, nígbà tí àwùjọ, àṣà àti èdè sì dàbí ààrò mẹ́ta tí kí í da ọbẹ̀ nù.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adeniji, D. A. (n.y.) Iṣẹ́ Irin Wíwà àti Irin Sísun. *Iṣẹ́ Iṣẹ̀ǹbáyé.* Ilésanmí, T. M. (Ed.), 1–16.

Aggrey, J. E. K. (1875-1927). *Excepts from Gallery of Gold Coast Celebrities.* Ghana: Dr. L. S. Ephraim & ILEN Publications Ltd.

## *Ọ̀PÁǸBÀTA*


Akíyẹmí, T. (n.y.) Iṣẹ́ Arọ́. *Iṣẹ́ Iṣẹ̀ǹbáyé.* Ilésanmí, T. M. (Ed.), 16–37

Arowolo, D. (2010). The Effects of Western civilization and culture on Africa. *AfroAsian Journal of Social Sciences* 1(1), Quarter IV.

Mákindé, S. O., Pemede̍́, O. and Amosu, A. (2013). 'The Value of Nigerian Culture in Educational Development. *African Journal of Pedagogy*. 6, 65-77.

Mákindé, S. O. (2018). Àgbéyẹ̀wò *Àtupalẹ̀ Òwe Yorùb*a´tí Amòfin Sunday Àjàyí Sófọláhàn Ṣe. Book Review presented at the 70th Birthday Ceremony of Sunday Àjàyi´Sofolahàn held at Okay Event Centre, Ibarà, Abeokúta, July 14, 2018.

Owólabí, K. (2021). Àbọ̀ Ìwádìí tí Ibi Iṣẹ́ fún Ọ̀nà Ìṣàmúlò Èdè Yorùbá gbé jáde ní ibi Àjọ̀dún Ìdàgbàsókè Ìran Yorùbá Lágbàáyé Alákọ̀ọ́kọ́: Ìpàtẹ Ìwé lórí Yorùbá tí a ṣe ní International Conference Centre, University of Ibadan láti 06/04/2021 sí 09/04/2021.

Bébà àpilèkọ fún Ayeye Àṣà Ọlọ́dọọdún (Àkòrí: Ibi Gíga) ti Ẹgbẹ́ Akẹ́kọ̀ọ́ Èdè Yorùba´ati´ Ẹkọ́ Ìkànsíraẹni (Yoruba and Communication Arts Association) Ẹ̀ka Ìmọ̀ Èdè Afíríkà, Lítíréṣọ̀ and Ẹ̀kọ́ Ìkànsíraẹni ni Yunifasiti Ìpínlẹ̀ Èkó ni Ọjọ́ Kọkàdínlógún, Oṣù Karùn-ún, Ọdún 2021.